# Àkíyèsí Àwọn Ìṣe Àṣírí ti Mercy Health Services

**ÀKÍYÈSÍ YÌÍ ṄṢE ÀPÈJÚWE BÍ A TI LÈ LO ÀLÀYÉ ÌṢÈGÙN NÍPA RẸ KÍ A SÍ SỌ Ọ́ DI MÍMỌ̀ ÀTI BÍ O TI LÈ NÍ ÀNFÀÀNÍ SÍ ÀLÀYÉ YÌÍ. JỌ̀WỌ́ FI PẸ̀LẸ́PẸ̀LẸ́ GBÉ E YẸ̀WÒ.**

**Òfin béèrè pé kíMercy Health Services** (MHS) pa àṣírí nípa àlàyé tí ó lè fini hàn tí ó níí ṣe pẹ̀lú ìlera àfojúrí tàbí ti ọpọlọ, ìtọ́jú ìlera tí o ti gbà, tàbí owó sísan fún ìtọ́jú rẹ mọ́. Gẹ́gẹ́ bí òfin ti pè fún, Àkíyèsí yìí npèsè àlàyé nípa àwọn ẹ̀tọ́ rẹ àti àwọn ojúṣe wa lábẹ́ òfin àti àwọn ìṣe àṣírí nípa àláyé ìlera rẹ fún ọ. Bákan náà Àkíyèsí yìí nṣe àpèjúwe bí MHS ti lè lò tàbí sọ àlàyé ìlera rẹ di mímọ̀. Àwọn ibùdó tí ó fi ara mọ́ MHS, àwọn akọ́ṣẹ́-mọṣẹ́ ìtọ́jú ílera, àwọn òṣìṣẹ́, àwọn òṣìṣẹ́ ìṣègùn, àwọn tí ó ngba ìdánilẹ́kọ̀ọ́, àwọn akẹ́kọ̀ọ́, àti àwọn oníṣẹ́ àánú ti àjọ náà ni yóò tẹ̀lé àwọn ìṣe àṣírí tí a ṣe àpèjúwe rè nínú Àkíyèsí yìí.  Ní àfikún, àwọn àjọ, ibùdó, tàbí àwọn ọlọ́dọ́nni lè ṣe alábàápín àlàyé ìlera pẹ̀lú ara wọn àti àwọn àjọ ìlera míràn tí wọ́n fi ara mọ́ MHS gẹ́gẹ́ bí ara ètò ìtọ́jú ìlera tí a ṣ'ètò fún ìtọ́jú, owó sísan, àti àwọn iṣẹ́ ṣíṣe ti ìtọ́jú ìlera bí a ti ṣe àpèjúwe rẹ̀ nínú Àkíyèsí yìí tàbí tí òfin fi ààyè gbà.

## Bí A Ti Lè Lò Kí A Sì Sọ Àlàyé Ìṣègùn Nípa Rẹ Di Mímọ̀

MHS lè lò tàbí sọ àlàyé ìṣègùn nípa rẹ di mímọ̀, láì sí ìfọwọ́sí rẹ tí a kọ sílẹ̀ (tí a mọ̀ sí ìfúnniláṣẹ), fún àwọn èrèdí tí ó níí ṣe pẹ̀lú:

- **Ìtọ́jú:** Ìtọ́jú túmọ̀ sí ṣíṣe àbójútó ìtọ́jú rẹ láarín onírúurú àwọn olùpèsè ìtọ́jú ìlera àti àwọn akọ́ṣẹ́-mọṣẹ́ fún ìjíròrò. Fún àpẹẹrẹ, akọ́ṣẹ́-mọṣẹ́ kan tí ó nṣe ìtọ́jú rẹ fún ẹsẹ̀ tí ó kán lè nílò láti mọ̀ bóyá o ní àìsàn ìtọ̀ ṣúgà nítorí pé àìsàn ìtọ̀ ṣúgà lè jẹ́ kí sísan egbò falẹ̀. Nítorí náà, akọ́ṣẹ́-mọṣẹ́ náà lè ṣe àgbéyẹ̀wò àwọn àkọsílẹ̀ ìṣègùn láti ọ̀dọ̀ olùpèsè ìtọ́jú rẹ àkọ́kọ́ láti ṣe ìgbéléwọ̀n bóyá o ní àwọn ipò àìsàn tí ó lè fẹjú kẹkẹ bí àìsàn ìtọ̀ ṣúgà.
- **Owó sísan:** Owó sísan ntọ́ka sí àwọn iṣẹ́ ṣíṣe tí wọ́n níí ṣe pẹ̀lú jíjẹ́rìísí ipele àwọn àjẹmọ́nú ìdójútòfò rẹ, bíbéèrè fún ìfúnnilàṣẹ fún ìtọ́jú àti dídarí sí ibòmíràn fún àwọn àkànṣe àyẹ̀wò, àti àwọn èrèdí ìdíyeléni/ìṣàkóso. Fún àpẹẹrẹ, MHS lè nílò láti pèsè àlàyé fún ètò ìdójútòfò rẹ nípa ipò ìṣègùn rẹ kí wọ́n lè mọ̀ bóyá apá ká ìlànà ìtọ́jú tí wọ́n ní lọ́kàn.
- **Àwọn Iṣẹ́ Ṣíṣe Ìtọ́jú Ìlera:** Àwọn iṣẹ́ ṣíṣe ìtọ́jú ìlera ntọ́ka sí àwọn iṣẹ́ ṣíṣe ti ìṣàkóso àti iṣẹ́ ti MHS gbọ́dọ̀ kópa nínú rẹ̀, títí kan àgbéyẹ̀wò ìdárasí, ìbójútó ìṣẹ̀lẹ̀, yíyẹ ìwé owó wò, àti àgbéyẹ̀wò ìṣègùn. Fún àpẹẹrẹ, MHS lè loàlàyé ìṣègùn rẹ láti ṣe àgbéyẹ̀wò ìṣesí àwọn òṣìṣẹ́ wa ní ti ṣíṣe ìtọ́jú rẹ.
- **Ṣíṣe Pàṣípààrọ̀ Àlàyé:** MHS lè ṣe alábàápín àlàyé tí a gbà tàbí ṣẹ̀dá nípa rẹ pẹ̀lú àwọn olùpèsè ìtọ́jú ìlera tàbí àwọn àjọ ìtọ́jú ìlera míràn, bí òfin ti fi ààyè gbà á, nípasẹ̀ àwọn Pàṣípààrọ̀ Àlàyé Ìlera (àwọn HIE) nínú èyí tí a ti nkópa.  HIE jẹ́ àgbékalẹ̀ ìmọ̀ ẹ̀rọ kan tí ó nfi ààyè gba pàṣípààrọ̀ àlàyé ìṣègùn lórí ẹ̀rọ tí ó ní ààbò láarín àwọn àjọ tí ó nkópa, bí àwọn ilé ìwòsàn, àwọn ọ́fíìsì oníṣègùn, àwọn yàrá àyẹ̀wò, àwọn ibùdó ìyàwòrán, àti àwọn olùpèsè ìṣègùn míràn.  Nípa ṣíṣe pàṣípààrọ̀ àlàyé nípasẹ̀ àwọn HIE, ó máa npèsè ìráàyèsí tí ó yára sí àlàyé ìṣègùn nípa rẹ fún MHS àti àwọn olùpèsè ìtọ́jú ìlera míràn, èyí tí ó nfi ààyè gbà wọ́n láti ṣe ìpinnu tí a túbọ̀ fi òye ṣe kíwọ́n sì ṣe àbójútó ìtọ́jú rẹ. MHS máa nkópa nínú Chesapeake Regional Information System for our Patients, Inc. (CRISP), HIE kan tí ó kárí ìpínlẹ̀. Gẹ́gẹ́ bí òfin ti fi ààyè gbà á, a ó ṣe alábàápín àlàyé ìlera rẹ pẹ̀lú HIE yìí láti pèsè ìráàyèsí kánkán, àbójútó ìtọ́jú tí ó dára síi, kí a sì ran àwọn olùpèsè àti àwọn òṣìṣẹ́ ìlera ìjọba lọ́wọ́ láti ṣe ìpinnu tí ó túbọ̀ ní òye síi. O lè "jáde" kí o sì dènà fífi CRISP wá àlàyé ìlera rẹ nípa pípe 1-877-952-7477 tàbí dídáhùn àwọn ìbéèrè inú àti fífi fọ́ọ̀mù Jíjáde kan kalẹ̀ sí CRISP nípasẹ̀ ímeèlì, fáàksì tàbí nípasẹ̀ wẹ́bsáìtì wọn ní www.crisphealth.org.  Tí o bá jáde ní CRISP, àwọn àlàyé ìlera kan nípa rẹ ṣì lè wà ní àrọ́wọ́tó nípasẹ̀ HIE bí òfin ti fi ààyè gbà á.  Fún àpẹẹrẹ, àwọn olùpèsè ìṣègùn tí wọ́n nkópa nínú CRISP yóò ṣì lè ráàyè sí àwọn àbájáde ilé àyẹ̀wò, àwọn àbájáde àwòrán yíyà, àti àwọn dátà míràn wọ́n sì lè fi àlàyé yìí ránṣẹ́ sí àwọn olùpèsè míràn tí a ti darí rẹ sí fún ìtọ́jú nípasẹ̀ àwọn iṣẹ́ ìtọ́jú iṣẹ́-rírán CRISP tí ó ní ààbò. Ní àfikún, ìjábọ̀ ìlera ìjọba àti àlàyé nípa ìlò nnkan olóró tí a darí, gẹ́gẹ́ bí ara Ètò Àbójútó Oògùn ti Maryland, yóò ṣì wà ní àrọ́wọ́tó fún àwọn olùpèsè nípasẹ̀ CRISP. MHS tún nkópa nínú àwọn HIE míràn, títí kan nípasẹ̀ ìlànà àwọn àkọsílẹ̀ ìṣègùn orí ẹ̀rọ (EMR) rẹ̀.  Èyí máa nfi ààyè gba MHS láti ṣe alábàápín tàbí gba àlàyé ìṣègùn nípa rẹ fún èrèdí ìtọ́jú, owó sísan, tàbí ìtọ́jú ìlera.  O ní ànfààní láti jáde kúrò nínú àwọn HIE míràn yìí. Fún àlàyé síi nípa bí o ti lè jáde, kàn sí Òṣìṣẹ́ Àṣírí MHS, tí àlàyé kíkàn síni rẹ̀ wà ní ìsàlẹ̀ yìí.
- **Àkọsílẹ̀ Ilé-iṣẹ́:** Tí a bá gbà ọ́ wọlé fún ìtọ́jú ní Mercy Medical Center tàbí Stella Maris, MHS lè fi àwọn àlàyé kọ̀ọkan tí ó ní gbèndéke sí ara àkọsílẹ̀ ilé-iṣẹ́ rẹ̀, títí kan orúkọ, ibùdó, ipò rẹ lápapọ̀, àti ẹ̀sìn tí o fi ara mọ́.  MHS lè sọ àlàyé àkọsílẹ̀ ilé-iṣẹ́ di mímọ̀ fún àwọn òjíṣẹ́ Ọlọ́run tàbí, àyàfi fún ti ẹ̀sìn tí a fi ara mọ́, fún àwọn tí ó fi orúkọ béèrè rẹ.  Tí ó bá jẹ́ pé o tako fífi àlàyé rẹ sínú àkọsílẹ̀ ilé-iṣẹ́, ó yẹ kí o sọ fún òṣìṣẹ́ ìforúkọsílẹ̀ ní àkókò ìforúkọsílẹ̀, kàn sí Ọ́fíìsì Ìgbaniwọlé ní 410-332-9801 tàbí kí o gba olùtọ́jú rẹ ní ìmọ̀ràn nípa àwọn ohun tí o yàn láàyò. Tí o ò bá sí ní àrọ́wọ́tó, MHS yóò lo òye akọ́ṣẹ́-mọṣẹ́ láti ṣe ìpinnu bóyá yóò pé ọ láti fi àlàyé rẹ sínú àkọsílẹ̀ náà.
- **Àwọn Mọ̀lẹ́bí àti àwọn Ọlọ́dọ́nni Míràn Tí Ó Lọ́wọ́ Nínú Ìtọ́jú Rẹ:** Àyàfi tí o bá takò ó, MHS lè sọ àlàyé ìṣègùn rẹ di mímọ̀ fún àwọn mọ̀lẹ́bí tàbí àwọn ènìyàn míràn tí ó lọ́wọ́ nínú ìtọ́jú ìṣègùn rẹ tàbí tí ó nràn ọ́ lọ́wọ́ láti sanwó fún ìtọ́jú rẹ, tí ó bá jẹ́ pé àlàyé náà ní nnkan íṣe pẹ̀lú ìlọ́wọ́sí ẹni náà nínú ìtọ́jú rẹ.  MHS tún lè fi ààyè gbà wọ́n láti ṣa àwọn ìpèsè ìṣègùn, àwòrán ẹ̀yà ara, tàbí ìwé oògùn tí a kọ ní orúkọ rẹ. Tí o ò bá r'áyè, MHS yóò lo òye akọ́ṣẹ́-mọṣẹ́ láti ṣe ìpinnu ohun tí yóò pé ọ jùlọ.
- **Yíyan Àwọn Olùránnilétí àti Àwọn Ọ̀nà Ìtọ́jú Míràn:** MHS lè kàn sí ọ láti rán ọ létí nípa àwọn ààyè tí o gbà sílẹ̀ kí ó sì pe àkíyèsí rẹ sí àwọn ọ̀nà ìtọ́jú míràn àti àwọn ànfààní àti iṣẹ́ ìtọ́jú míràn tí ó níí ṣe pẹ̀lú ìlera.
- **Ìkówójọ:** MHS lè sọ àwọn àlàyé nípa rẹ di mímọ̀ fún Mercy Health Foundation, àwọn déètì tí o gba àwọn iṣẹ] ìtọ́jú láti MHS, ẹ̀ka MHS tàbí olùpèsè tí o ti gba ìtọ́jú, orúkọ olùpèsè tí ó nṣe ìtọ́jú rẹ, àbájáde ìtọ́jú rẹ, àti ipò ìdójútòfò rẹ.  A lè kàn sí ọ gẹ́gẹ́ bí ara àwọn ìgbìyànjú ìkówójọ wa láti ṣe àtìlẹ́yìn iṣẹ́ ètò ìlera wa. O ní ẹ̀tọ́ láti jáde kúrò nínú gbígba àwọn ìbánisọ̀rọ̀ bẹ́ẹ̀ nípa fífi tó Mercy Health Foundation létí ní 410-332-9873 tàbí ní updatemyrecord@mdmercy.com.
- **Ìfi Ẹ̀yà Ara Tọrẹ:** MHS lè sọ àlàyé ìṣègùn rẹ di mímọ̀ fún àwọn àjọ tí ó nbójútó rírà àti fífi ẹ̀yà ara tọrẹ.
- **Àwọn Aláṣẹ Ológun:** Tí o bá jẹ́ ọmọ ẹgbẹ́ Ológun Ilẹ̀ Amẹ́ríkà tàbí ológun ilẹ̀ òkèèrè, MHS lè jọ̀wọ́ àlàyé ìṣègùn nípa rẹ fún àwọn aláṣẹ ilé iṣẹ́ ológun tí ó yẹ.

- **Owó Ọ̀yà Àwọn Ọ̀ṣìṣẹ́:** MHS lè sọ àláyé ìṣègùn di mímọ̀ láti tẹ̀lé àwọn òfin owó ọ̀yà àwọn ọ̀ṣìṣẹ́.
- **Àwọn Iṣẹ́ Ṣíṣe Ìlera Àwùjọ:** MHS lè sọ àlàyé ìṣègùn rẹ di mímọ̀ fún àwọn ọ̀ṣìṣẹ́ ìlera àwùjọ fún èrèdí ìlera àwùjọ, títí kan dídènà tàbí ṣíṣe àdínkù sí àìsàn, ìfarapa, tàbí dídi aláàbọ̀ ara; jíjábọ̀ lílo ọmọdé ní ílòkulò tàbí kíkọ̀ ọ́ sílẹ̀; jíjábọ̀ àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ ibi tàbí àléébù ọjà fún Ẹ̀ka Ìṣàkóso Onjẹ àti Oògùn Ilẹ̀ Amẹ́ríkà; kí ó sì fi tó àwọn ènìyàn tí wọ́n lè ti fi ojú winá àìsàn kan tàbí tí wọ́n lè wà nínú ewu níní tàbí títan àìsàn kan káàkiri.
- **Àbójútó Ìlera:** MHS lè sọ àlàyé ìṣègùn rẹ di mímọ̀ fún àwọn àjọ ìjọba àpapọ̀ tàbí ti ìpínlẹ̀ tí wọ́n nbójútó ìlànà ìtọ́jú ìlera, àwọn ètò ìjọba, àti ìmúṣẹ àwọn òfin ẹ̀tọ́ ará ìlú fún yíyẹ ìwé wò, ìwádìí, tàbí àbẹ̀wò.
- **Àwọn Ìgbẹ́jọ́ Òfin:** MHS lè sọ àlàyé ìṣègùn rẹ di mímọ̀ fún àwọn ilé ẹjọ́ àti àwọn agbẹjọ́rò ní ìfèsì sí òfin ilé ẹjọ́, àṣẹ láti fi ara hàn ní ilé ẹjọ́, tàbí àwọn ìgbésẹ̀ míràn tí ó bá òfin mu, láti jẹ́rìí gbe ara wa tako ìpẹ̀jọ́ kan.
- **Mímú Òfin Ṣẹ:** MHS lè sọ àlàyé ìṣègùn rẹ di mímọ̀ fún àwọn ọ̀ṣìṣẹ́ agbófinró gẹ́gẹ́ bí òfin ti fún wọn láàyè tàbí pè fún láti ṣe ìrànlọ́wọ́ fún wíwá ọ̀daràn tàbí ìsánsá kan tàbí ìwádìí ìwà ọ̀daràn.
- **Àwọn Olùwádìí Ikú, Àwọn Olùṣàyẹ̀wò Ìṣègùn, àti Àwọn Olùdarí Ìsìnkú:** MHS lè sọ àlàyé ìṣègùn rẹ di mímọ̀ láti dá ènìyàn kan tí ó kú mọ̀, mọ okùnfà ikú, kí wọ́n sì ṣe ìrànlọ́wọ́ fún àwọn olùdarí ìsìnkú láti ṣe ojúṣe wọn.
- **Ààbò Orílẹ̀-èdè:** MHS lè sọ àlàyé ìṣègùn rẹ di mímọ̀ fún àwọn aláṣẹ ìjọba àpapọ̀ tí a fún ní àṣẹ fún iṣẹ́ ọ̀tẹ̀lẹ̀múyẹ́ tàbí àwọn iṣẹ́ ṣíṣe ààbò orílẹ̀-èdè míràn bí òfin ti fi ààyè gbà á.
- **Àwọn Ẹlẹ́wọ̀n àti Àwọn Ènìyàn Tí Wọ́n Wà Ní Àtìmọ́lé:** Tí o bá jẹ́ ọ̀kan lára àwọn èrò ibùdó àtúnṣe tàbí o wà ní àtìmọ́lé àwọn agbófinró, MHS lè jọ̀wọ́ àlàyé ìṣègùn rẹ fún ibùdó àtúnṣe tàbí òṣìṣẹ́ agbófinró bí òfin ti fi ààyè gbà á tàbí pè fún.
- **Ìwádìí:** MHS lè lò tàbí sọ àlàyé ìṣègùn rẹ di mímọ̀ fún àwọn èrèdí ìwádìí lábẹ́ àwọn òfin kan ní pàtó tí òfin àṣírí tí ó bá a wí pèsè fún. MHS lè lò tàbí sọ àlàyé ìṣègùn rẹ di mímọ̀ fún àwọn olùwádìí tí ó bá jẹ́ pé a ti fi ọwọ́ sí wọn nípasẹ̀ àkànṣe ìlànà àgbéyẹ̀wò kan tí a gbé kalẹ̀ láti dá ààbò bo àìléwu, ìgbáyé-gbádùn, àti àṣírí agbàwòsàn.
- **Àwọn Ìhàlẹ̀ Mọ́ Ìlera tàbí Àìléwu:** Gẹ́gẹ́ bí òfin àti ìhùwàsí tí ó bá a wí ti fi ààyè gbà á, MHS lè lò kí ó sì sọ àlàyé ìṣègùn di mímọ̀ tí ó bá gbàgbọ́, pẹ̀lú inúure, pé irú ìlò tàbí ìsọdimímọ̀ bẹ́ẹ̀ ṣe kókó láti dènà ìfarapa tí ó le fún ọ tàbí àwọn ẹlòmíràn. Bàkan náà a lè ṣe alábàápín àlàyé rẹ fún àwọn ìgbìyànjú ìdónlà ẹ̀mí ní àkókò àjálù tàbí ní àwọn ààyè pàjáwìrì.
- **Àwọn Alájọṣe Okòwò:** MHS lè sọ alàyé ìṣègùn rẹ di mímọ̀ fún àwọn okòwò ní ìta tí a mọ̀ sí "àwọn alájọṣe okòwò" tí wọ́n npèsè àwọn iṣẹ́ ìtọ́jú lórúkọ rẹ̀, bíi iṣẹ́ ìtọ́jú dídá iye lé tàbí bíbáni jíròrò.
- **Àwọn Àkọsílẹ̀ Àìlera Nnkan Lílò:** Àwọn kan lára àkọsílẹ̀ ìṣègùn wa lè wà lábẹ́ 42 C.F.R. Apá 2, tí ó bá àwọn àkọsílẹ̀ ìtọ́jú àìlera ìlò nnkan kan wí (“Àwọn Àkọsílẹ̀ Apá 2”). MHS kò níí lò àti/tàbí sọ di mímọ̀ àwọn Àkọsílẹ̀ Apá 2 fún èrèdí ìtọ́jú, owó sísan, tàbí iṣẹ́ ṣíṣe ìtọ́jú ìlera (TPO) láì gba ìfọwọ́sí rẹ tí ó péye. MHS lè sọ irú àwọn àkọsílẹ̀ bẹ́ẹ̀ di mímọ̀ lẹ́ẹ̀kejì ní ìbámu pẹ̀lú Òfin Àṣírí fún àwọn àjọ tàbí ènìyàn tí ó wà ní ìpamọ́ fún TPO. Ìsọ di mímọ̀ yòówù lábẹ́ àwọn òfin náà gbọ́dọ̀ pin sí àlàyé tí ó ṣe kókó láti ṣe ojúṣe sísọ di mímọ̀ yẹn. MHS lè lò/sọ àwọn Àkọsílẹ̀ Apá 2 di mímọ̀ láì sí ìfọwọ́sí rẹ fún àwọn aláṣẹ ìlera ará ìlú tàbí ti àbójútó ìlera, fún èrèdí ìwádìí, ní ti pàjáwìrì ìṣègùn, àti fún àwọn olùpèsè iṣẹ́ ìtọ́jú wa tí wọ́n ti fi ẹnu kò sí àwọn àmúyẹ àṣírí kan. MHS kò ní lò/sọ àwọn Àkọsílẹ̀ Apá 2 di mímọ̀ tàbí pèsè ẹ̀rí tí yóò fi àwọn àkóónú irú àwọn àkọsílẹ̀ bẹ́ẹ̀ ránṣẹ́ nínú ìgbẹ́jọ́ ará ìlú, ti ìwà ọdaràn, ti ìṣàkóso, tàbí ti ṣíṣe òfin èyí tí aláṣẹ Ìjọba Àpapọ̀, Ìpínlẹ̀, tàbí ìbílẹ̀ ṣe lòdì sí ọ tàbí láti ṣe ìwádìí tàbí fà ọ́ lọ sí ilé ẹjọ́ láì sí ìfọwọ́sí rẹ tàbí àṣẹ ilé ẹjọ́. A tún nílò ìfọwọ́sí ọ̀tọ̀ tí ó péye láti lò kí a sì sọ àwọn àfiyèsí ìgbaninímọ̀ràn SUD di mímọ̀. Sísọ di mímọ̀ kọ̀ọ̀kan tí MHS ṣe yóò ní ẹ̀dà ìfọwọ́sí àti/tàbí àlàyé tí ó yè kooro nípa bí ìfọwọ́sí náà ti tó. Gẹ́gẹ́ bí ó ti bá àwọn Àkọsílẹ̀ Apá 2 wí, o ní ẹ̀tọ́ láti béèrè fún àkọsílẹ̀ sísọ àwọn àkọsílẹ̀ di mímọ̀ èyí tí ó kan àwọn sísọ di mímọ̀ tí a ṣe ní ọdún mẹ́ta ṣáájú déètì ìbéèrè náà títí kan àwọn sísọ di mimọ̀ tí a ṣe láì sí ìfọwọ́sí rẹ àti fún TPO nígbà tí a sọ irú TPo bẹ́ẹ̀ di mímọ̀ nípasẹ̀ àkọsílẹ̀ ìlera orí ẹ̀rọ, ẹ̀tọ́ láti béèrè fún gbèndéke sísọ di mímọ̀, títí kan àwọn ètò ìlera fún (àwọn) iṣẹ́ ìtọ́jú tí o sanwó rẹ[ ní kíkún, ẹ̀tọ́ láti jáde kúrò nínú àwọn ìbánisọ̀rọ̀ kíkó owó jọ, ẹ̀tọ́ láti gba àwọn ìfitónilétí àìṣedéédé, àti ẹ̀tọ́ láti fi ẹ̀sùn sùn fún títa ìpá sí Apá 2. Àwọn Àkọsílẹ̀ Apá 2 tí a bá sọ di mímọ̀ ní ìbámu pẹ̀lú Òfin Àṣírí lè wà lábẹ́ sísọ di mímọ̀ lẹ́ẹ̀kejì Òfin Àṣírí kò sì níí dá ààbò bò ó.

## Lílò àti Sísọ Di Mímọ̀ Tí Ó Nnílò Ìfúnniláṣẹ Rẹ

Lílò àti sísọ di mímọ̀ àlàyé ìṣègùn tí a kò ṣe àpèjúwe rẹ̀ nínú Àkíyèsí yìí ni a ó ṣe pẹ̀lú ìfúnnilàṣẹ tí o kọ nìkan. Fún àpẹẹrẹ, pẹ̀lú àwọn ìyàsọ́tọ̀ tí ó ní gbèndéke, MHS gbọ́dọ̀ gba ìfúnnilàṣẹ rẹ ṣáájú: lílò àti sísọ di mímọ̀ àwọn àfiyèsí ìtọ́jú àrùn ọpọlọ àti àwọn àfiyèsì ìgbaninímọ̀ràn Àìlera Lílo Nnkan; lílò tàbí sísọ àlàyé ìṣègùn rẹ di mímọ̀ fún èrèdí ọjà títà (àyàfi fún àwọn ìbánisọ̀rọ̀ ojúkoojú tàbí àwọn ẹ̀bùn ìpolówó ọjà tí iye orí rẹ̀ kéré júlọ tí MHS pèsè fún ọ); tàbí títà tàbí gbígba ohunkóhun tí ó níye lórí ní pàṣípààrọ̀ fún àlàyé ìṣègùn rẹ. Bí o bá fún MHS l'àṣẹ láti lò tàbí sọ àlàyé ìlera rẹ di mímọ̀, o ní ẹ̀tọ́ láti fagi lé ìfúnnilàṣẹ náà ní àkókò yòówù nípa pípèsè àkíyèsí tí a fi ọwọ́ kọ fún Ọ̀ṣìṣẹ́ Àṣírí MHS tí àlàyé kíkàn síni rẹ̀ wà ní ìsàlẹ̀ yìí. Fífagi lé e rẹ yóò bẹ̀rẹ[ iṣẹ́ ní kété tí wọ́n bá ti rí i gbà, ṣùgbọ́n kò níí ní ipa lórí àwọn ìlò àti sísọ di mímọ̀ tí MHS ṣe ní àkókò tí ìfúnnilàṣẹ rẹ ṣì nṣiṣẹ́ lọ́wọ́.

## Àwọn Ẹ̀tọ́ Rẹ Nípa Àlàyé Ìṣègùn Nípa Rẹ
O ní àwọn ẹ̀tọ́ yìí nípa àlàyé ìṣègùn tí MHS ntọ́jú nípa rẹ:

- **Ẹ̀tọ láti Ṣe Àbẹ̀wò kí o sì Ṣe Ẹ̀dà Rẹ̀.** O ní ẹ̀tọ́ láti ṣe àbẹ̀wò àti/tàbí gba ẹ̀dà àlàyé ìlera àti ti ìdíyelé rẹ tí MHS lò láti ṣe àwọn ìpinnu ìtọ́jú ìlera nípa rẹ. Bákan náà ni o ní ẹ̀tọ́ láti béèrè pé kí MHS fi ẹ̀dà àwọn àkọsílẹ̀ ìṣègùn rẹ ránṣẹ́ sí alàgàta kan. Tí o bá fẹ́ ṣe àgbéyẹ̀wò tàbí gba ẹ̀dà àwọn àkọsílẹ̀ rẹ, o gbọ́dọ̀ béèrè fún u nípa kíkọ ìwé sí olùpèsè rẹ tàbí ẹ̀ka àkọsílẹ̀ ìṣègùn tí ó yẹ.
- **Ẹ̀tọ́ láti Béèrè fún Àtúnṣe.** Bí o bá gbàgbọ́ pé àlàyé ìṣègùn tí MHS ntọ́jú nípa rẹ kò péye tàbí kò pé, o lè béèrè pé kí MHS ṣe àtúnṣe àlàyé náà. O gbọ́dọ̀ béèrè àtúnṣe náà nípa ìwé kíkọ sí olùpèsè rẹ tàbí sí ẹ̀ka àkọsílẹ̀ ìṣègùn tí ó yẹ. Bí MHS bá gba ìbéèrè rẹ, MHS yóò fi tó ọ létí yóò sì fi àfikún àlàyé náà kún àkọsílẹ̀ rẹ nípasẹ̀ ṣíṣe àfikún. MHS kò lè pa ohun tí ó wà nínú àkọsílẹ̀ náà rẹ́. Tí MHS bá fi ìbéèrè rẹ dù ọ́, a ó pèsè àlàyé ìfiduni náà àti àwọn ẹ̀tọ́ rẹ.
- **Ẹ̀tọ́ sí Ìsirò àwọn Ìsọ Di Mímọ̀.** O ní ẹ̀tọ́ láti gba àkọsílẹ̀ àwọn ìsọ di mímọ̀ tí MHS ti ṣe nípa àlàyé ìṣègùn rẹ ní ọdún mẹ́fà ṣáájú ìbéèrè rẹ. Àkọsílẹ̀ àwọn sísọ di mímọ̀ kò níí ní gbogbo sísọ di mímọ̀ tí a ṣe, títí kan àwọn ìsọ di mímọ̀ tí a ṣe fún ìtọ́jú, owó sísan, àwọn iṣẹ́ ṣíṣe ìtọ́jú ìlera, àwọn sísọ di mímọ̀ tí o fi àṣẹ sí, àti àwọn ìsọ di mímọ̀ tí a ṣe fún ọ. Láti béèrè fún ṣíṣe ìsirò àwọn ìsọ di mímọ̀, fi ìbéèrè kan tí a fi ọwọ́ kọ kalẹ̀ fún Olùdarí Àwọn Iṣẹ́ Ìtọ́jú Àlàyé Ìlera nípasẹ̀ fáàksì sí 410-332-0336 tàbí nípasẹ̀ ímeèlì: Fún Àkíyèsì Health Information Services Department, Mercy Medical Center, 301 St. Paul Place, Baltimore, MD 21202.
- **Ẹ̀tọ́ láti Béèrè Fún Gbèndéke.** O ní ẹ̀tọ́ láti béèrè pé kí MHS fi gbèndéke sí bí ó ti nlò àti sísọ di mímọ̀ àlàyé ìlera rẹ fún ìtọ́jú, owó sísan, tàbí àwọn iṣẹ́ ṣíṣe ti ìtọ́jú ìlera, tàbí pẹ̀lú àwọn mọ̀lẹ́bí tàbí àwọn ẹlòmíràn tí ó lọ́wọ́ nínú ọ̀ràn rẹ. A ò pè fún pé kí MHS téwọ́ gba gbèndéke tí o béèrè fún àyàfi tí ó bá ní nnkan íṣe pẹ̀lú sísọ di mímọ̀ tí a ṣe fún olùdójútòfò ìlera rẹ tí ó ní íṣe pẹ̀lú iṣẹ́ ìtọ́jú kan pàtó èyí tí o ti sanwó fún ní ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ tẹ̀lẹ̀; ṣùgbọ́n, tí iṣẹ́ ìtọ́jú náà bá jẹ́ ara ìsọ̀rí àwọn iṣẹ́ ìtọ́jú tí a "dìpọ̀" fún érèdí ìdíyelé ètò ìlera, ó lè má ṣeéṣe fún MHS láti fi gbèndéke sí sísọ di mímọ̀ náà. Tí MHS bá fi ara mọ́ gbèndéke náà, a ó fi tó ọ létí nípa ìwé kíkọ, MHS yóò sì ṣe ohun tí o béèrè àyàfi tí ó bá jẹ́ pé nṣe ni a nílò àlàyé ìṣègùn náà láti pèsè ìtọ́jú pàjáwìrì fún ọ tàbí òfin pè fún kí a sọ ọ́ di mímọ̀. Láti béèrè fún gbèndéke, fi ìbéèrè tí a fi ọwọ́ kọ kalẹ̀ tí ó nṣe àlàyé gbèndéke tí o béèrè fún fún Ọ̀ṣìṣẹ́ Àṣírí MHS.
- **Ẹ̀tọ́ láti Béèrè Ìbánisọ̀rọ̀ Àṣírí**. O ní ẹ̀tọ́ láti béèrè pé kí MHS kàn sí ọ nípa àlàyé tàbí àwọn iṣẹ́ ìtọ́jú ìṣègùn rẹ nípa lílo àwọn ọ̀nà kan (ìyẹn ni MyChart, ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀, ìfiwéránṣẹ́) tàbí ní ibùdó kan. MHS yóò bu ọlá fún àwọn ìbéèrè tí ó mú ọgbọ́n wá ní àkókò tí ó bá ṣeéṣe. Láti béèrè fún ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ míràn, fi ìbéèrè tí a fi ọwọ́ kọ kalẹ̀ fún olùpèsè rẹ tàbí Ọ̀ṣìṣẹ́ Àṣírí MHS.
- **Ẹ̀tọ́ láti Gba Ẹ̀dà Oní Pépà ti Àkíyèsí Yìí**. O ní ẹ̀tọ́ láti gba ẹ̀dà oní pépà ti Àkíyèsí yìí ní àkókò yòówù. Láti gba ẹ̀dà kan, kàn sí olùpèsè rẹ tàbí Ọ̀ṣìṣẹ́ Àṣírí MHS.
- **Ẹ̀tọ́ láti Fi Àìṣedéédé Tóni Létí**. A pè fún kí MHS fi àìṣedéédé àlàyé ìṣègùn rẹ tí a kò dá ààbò bò tó ọ létí.

## Àwọn Ìyípadà sí Àkíyèsí Yìí
Àkíyèsí yìí nbẹ̀rẹ̀ iṣẹ́ ní Ọjọ́ 16 Oṣù Kejì, Ọdún 2026. MHS gbọ́dọ̀ tẹ̀lé àwọn àjọsọ inú Àkíyèsí tí ó wà lẹ́nu iṣẹ́ lọ́wọ́lọ́wọ́. MHS ní ẹ̀tọ́ láti ṣe ìyípadà sí àwọn ìṣe àṣírí rẹ̀ àti Àkíyèsí yìí ní àkókò yòówù, ó sí lè jẹ́ kí àwọn àjọsọ tuntun náà bẹ̀rẹ̀ iṣẹ́ fún gbogbo àlàyé ìṣègùn tí MHS ntọ́jú fún ọ tẹ̀lẹ̀ àti àlàyé tí ó bá rí gbà ní ọjọ́ iwájú. Bí a bá yí àwọn nkan padà nínú Àkíyèsí náà, a ó gbé Àkíyèsí tí a mú dójú ìwọ̀n sórí ojú ewé ayélujára MHS ní https://mdmercy.com, tí a gbé jáde ní àwọn ibùdó tí ó hàn kedere tí ojú sì sọ jákèjádò àwọn sáìtì MHS tí a sì ṣe alábàápín wọn bí a ti pè fún.

## Àwọn Ìbéèrè tàbí Ẹ̀sùn
Tí o bá ní ìbéèrè nípa Àkíyèsí yìí tàbí o lérò pé a ti tàpá sí àwọn ẹ̀tọ́ àṣírí rẹ, jọ̀wọ́ kàn sí Ọ̀ṣìṣẹ́ Àṣírí MHS ní 301 St. Paul Place, Baltimore, MD 21202, Ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀: (410) 576-LAWS (5297), Ímeèlì: Compliance@mdmercy.com. Bákan náà o lè fi ẹ̀sùn sùn lọ́dọ̀ Akọ̀wé Ẹ̀ka Ìlera àti Àwọn Iṣẹ́ Ìtọ́jú Ọmọnìyàn Ilẹ̀ Amẹ́ríkà. A kò níí fi ìyà jẹ ọ́ tàbí gbẹ̀san lára rẹ fún fífi ẹ̀sùn sùn.

Gbogbo àwọn àjọ tí wọ́n jẹ́ ara àkópọ̀ tí wọ́n fi ara mọ́ MHS tí a mọ̀ ni ó ntẹ̀lé Àkíyèsí yìí, títí kan, ṣùgbọ́n tí kò pin sí:
Mercy Medical Center, Inc.; North Calvert Anesthesiology Services, LLC; Mercy Transitional Care Services, Inc.; Lutherville Hematology and Oncology Services, LLC; Stella Maris, Inc.; St. Paul Place Specialists, Inc.; Maryland Family Care, Inc.; Teresa Hoffman, M.D. and Associates, LLC; Vascular Specialty Services, LLC; Neurosurgical Specialty Services, LLC; The Emergency Room Physicians SPPS, LLC.

- **English:** ATTENTION: If you speak English, free language assistance services are available to you. Appropriate auxiliary aids and services to provide information in accessible formats are also available free of charge. Call 1-410-332-9000 (TTY: 1-410-332-9888) or speak to your provider.
- **Spanish:** ATENCIÓN: si habla español, tiene a su disposición servicios gratuitos de asistencia lingüística. Llame al 1-410-332-9000 (TTY: 1-410-332-9888).
- **Chinese:** 注意：如果您说中文，我们将免费为您提供语言协助服务。我们还免费提供适当的辅助工具和服务，以无障碍格式提供信息。致电 1-410-332-9000（文本电话：1-410-332-9888）或咨询您的服务提供商。
- **Korean:** 주의: 한국어를 사용하시는 경우, 언어 지원 서비스를 무료로 이용하실 수 있습니다. 1-410-332-9000 (TTY: 1-410-332-9888) 번으로 전화해 주십시오.
- **Russian:** ВНИМАНИЕ: Если вы говорите на русском языке, то вам доступны бесплатные услуги перевода. Звоните 1-410-332-9000 (телетайп: 1-410-332-9888).
- **Vietnamese:** LƯU Ý: Nếu bạn nói tiếng Việt, chúng tôi cung cấp miễn phí các dịch vụ hỗ trợ ngôn ngữ. Các hỗ trợ dịch vụ phù hợp để cung cấp thông tin theo các định dạng dễ tiếp cận cũng được cung cấp miễn phí. Vui lòng gọi theo số 1-410-332-9000 (Người khuyết tật: 1-410-332-9888) hoặc trao đổi với người cung cấp dịch vụ của bạn.
- **French:** ATTENTION : Si vous parlez Français, des services d'assistance linguistique gratuits sont à votre disposition. Des aides et services auxiliaires appropriés pour fournir des informations dans des formats accessibles sont également disponibles gratuitement. Appelez le 1-410-332-9000 (TTY : 1-410-332-9888) ou parlez à votre fournisseur.
- **Tagalog:** PAALALA: Kung nagsasalita ka ng Tagalog, magagamit mo ang mga libreng serbisyong tulong sa wika. Magagamit din nang libre ang mga naaangkop na auxiliary na tulong at serbisyo upang magbigay ng impormasyon sa mga naa-access na format. Tumawag sa 1-410-332-9000 (TTY: 1-410-332-9888) o makipag-usap sa iyong provider.
- **Amharic**: ማሳሰቢያ፦ አማርኛ የሚናገሩ ከሆነ፣ የቋንቋ ድጋፍ አገልግሎት በነፃ ይቀርብልዎታል። መረጃን በተደራሽ ቅርጸት ለማቅረብ ተገቢ የሆኑ ተጨማሪ እገዛዎች እና አገልግሎቶች እንዲሁ በነፃ ይገኛሉ። በስልክ ቁጥር 1-410-332-9000 (TTY:1-410-332-9888) ይደውሉ ወይም አገልግሎት አቅራቢዎን ያናግሩ።
- **Swahili:** MAKINIKA: Ikiwa wewe huzungumza Kiswahili, msaada na huduma za lugha bila malipo unapatikana kwako. Vifaa vya usaidizi vinavyofaa na huduma bila malipo ili kutoa taarifa katika mifumo inayofikiwa pia inapatikana bila malipo. Piga simu 1-410-332-9000 (TTY: 1-410-332-9888) au zungumza na mtoa huduma wako.
- **Nepali:** सावधान: यदि तपाईंनेपाली भाषा बोल्नुहुन्छ भनेतपाईंका लादि दन:शुल्क भादषक सहायता सेवाहरू उपलब्ध छन्। पहुँचयोग्य ढाँचाहरूमा जानकारी प्रिान िननउपयुक्त सहायता र सेवाहरू पदन दनिःशुल्क उपलब्ध छन्। 1-410-332-9000 (TTY: 1-410-332-9888) मा फोन िनुनहोस्वा आफ्नो प्रिायकसँुि कु रा िनुनहोस्।
- **Yoruba:** Tí o bá ń sọ èdè Yorùbá là ti orílè-èdè Nàìjíríà, Ànfànì Ògb'ifọ wà fún ọ ní ọ̀fẹ́. Àwọn ìròyìn àti ìkéde wa fún ọ ní ọ̀nà ti oyè ní ọ̀fẹ́ Fún ẹkúnréré, e pe ẹ̀rọ ìbáni sọ̀rọ̀ yìí: ookan -ẹẹjọ-eeje-eeje-eejì-ẹ̀ẹ̀san-eeje-eeji-eeji-ẹẹfa-ẹẹfa (1-410-332-9000) (TTY: 1-410-332-9888) kí o si ló onka idanimo oodo- ookan-ẹẹta- eeji- eeje - ookan - ẹẹrin- ookan- eeje- eeji- eeje tàbí ke ba olùpèsè yin ṣòrò.
- **Urdu:** توجہ دیں: اگر آپ اردو بولتے ہیں، تو آپ کے لیے زبان کی مفت مدد کی خدمات دستیاب ہیں۔ قابل رسائی فارمیٹس میں معلومات فراہم کرنے کے لیے مناسب معاون امداد اور خدمات بھی مفت دستیاب ہیں۔ 1-410-332-9000 (TTY: 1-410-332-9888) پر کال کریں یا اپنے فراہم کنندہ سے بات کریں۔
- **Farsi (Persian):** توجه :اگر زبان فارسی صحبت میکنید، خدمات پشتیبانی زبانی رایگان در دسترس شما قرار دارد .همچنین کمک‌ها و خدمات پشتیبانی مناسب برای ارائه اطلاعات در قالب‌های قابل دسترس، به‌طور رایگان موجود می‌باشند .با شماره 1-410-332-9000 (تله‌تایپ: 1-410-332-9888) تماس بگیرید یا با ارائه‌دهنده خود صحبت کنید.
- **Creole (Cape Verdean):** ATENÇÃO: Caso fale Kabuverdianu, existem serviços de assistência linguística gratuitos disponíveis. Estão também disponíveis apoios e serviços auxiliares adequados para prestar informações em formatos acessíveis. Ligue 1-410-332-9000 (TTY: 1-410-332-9888) ou contacte o seu operador.
- **Portuguese:** ATENÇÃO: Se você fala Português, serviços gratuitos de assistência linguística estão disponíveis para você. Auxílios e serviços auxiliares apropriados para fornecer informações em formatos acessíveis também estão disponíveis gratuitamente. Ligue para 1-410-332-9000 (TTY: 1-410-332-9888) ou fale com seu provedor.